# ILAANA ISE NI SAA KINNI FUN SS2

# YORUBA LANGUAGE

| OSE | AKORI EKO |
|---|---|
| 1 | EDE – Atunyewo lori Aroko ajemo isipaya:<br>i. Ilana ero aroko ajemo isipaya<br>ii. Akole, Ifaara, koko oro, agbalo gbdo<br>iii. Alaye kikun lori eto ipin afo<br>iv. Kiko aroko lori akole bii Omi, Iyan,Oja ati bee lo<br>ASA – Atunyewo lori eko ile:<br>i. Ibowofagba, ikini, bi o se ye ni gbogbo igba, suuru, otito sise, iforiti, igboran ati bee bee lo<br>LITIRESO – Itupale asayan iwe ti ajo WAEC/NECO yan ti rgbe Akomolede fi owo si. |
| 2 | EDE – Atunyewo lori silebu ede Yoruba:<br>i. Oriki silebu<br>ii. Silebu oni faweli kan (F)<br>iii. Silebu alakanpo konsonanti ati faweli<br>iv. Pipin oro si silebu<br>ASA – Atunyewo ise abinibi:<br>i. Ise agbe, gege bi ise abinibi gbogbo wa. Awon ohun elo ise agbe: Oko, Ada, ati bee bee lo<br>ii. Ise agbede, ise alapata, ise akope ati ise gbenagbena ati bee bee lo<br>LITIRESO – Itesiwaju lori atupale awon iwe Litireso:<br>i. Awon eda itan<br>ii. Ibudo itan |
| 3 | EDE – Atunyewo aroko onisorongbesi:<br>i. Alaye lori oro onisorongbesi<br>ii. Kiko aroko onisorongbesi to dale isele awujo<br>ASA – Ona ibanisoro:<br>i. Lilo awon eya ara fun ibanisoro bii sise ni ni eekanna, ori gbongbon, oju sise, ara mimi, titenimole, imu yinyin ati iparoko.<br>LITIRESO – Itupale iwe litireso:<br>Ahunpo itan ati awon asa Yoruba to seyo ninu itan naa |
| 4 | EDE – Atunyewo ihun oro<br>i. Siseda oro rouko<br>ii. Alaye lori awon oro oruko ti a ko seda sugbon ti won dabi eyi ti aseda bi ile, oba, omo, iay ati bee bee lo<br>ASA – Itesiwaju eko lori ona ibanisoro:<br>i. Ibanisoro ni aye ode oni bi iwe iroyin, telifonu, redio, foonu, foonu alagbekaa 1 meeli ati fasi (fax)<br>LITIRESO – Sise atupale asayan iwe litireso:<br>i. Awon ilo ede/Akanlo ede<br>ii. Sise orinkinniwin won |
| 5 | EDE – Onka Yoruba:<br>i. Lati egbaa de oke meedogbon on (2,000 – 500,000)<br>ASA – Awon orisa ile Yoruba:<br>i. Ogun, Obatala, Esu<br>ii. Awon ohun ti a fi n bo eon ati oriki okookan won |

| | |
|---|---|
| | LITIRESO – Kika iwe asayan ti ijoba yan |
| 6 | EDE – Onka Yoruba:<br>i. Lati oke meedogbon on de Aadota (500,000 – 1,000,000)<br>ASA – Awon orisa ile Yoruba ati bi a se n bo won:<br>i. Orunmila, Sango<br>ii. Awon ohun ti a fi n bo won ati oriki okookan won<br>LITIRESO – Kika sayan iwe litereso Yoruba ti ajo WAEC/NECO yan |
| 7 | EDE – Atunyewo awon eya ara ifo:<br>i. Lilo awon eya ara ifo<br>ii. Alaye lori afipe asunsi ati afipe akanmole<br>ASA – Awon orisa ati bi a se n bo won:<br>i. Awon orisa miiran ni agbegbe awon akeeko<br>ii. Ipo orisa ni ile Yourba<br>iii. Pataki orisa lawujo Yoruba<br>LITIRESO – Kika iwe litireso Yoruba ti ijoba yan |
| 8 | EDE – Atunyewo awon iro ninu ede Yoruba:<br>i. Iro faweli, iro konsonanti ati iro ohun<br>ASA – Ero ati igbagbo awon Yoruba lori Oso ati Aje:<br>i. Ise ti awon aje n se ninu isegun ati iwosan<br>LITIRESO – Kika iwe litireso ti ijoba yan |
| 9. | EDE – Atunyewo apejuwe iro konsonanti ati iro faweli:<br>i. Yiya ate faweli ati konsonanti<br>ii. Sise apejuwe awon iro konsonanti ati faweli leyo kookan<br>ASA – Ero ati igbagbo Yoruba lori akudaaya ati abami eda:<br>i. Akudaaya ati abami eda bii Egbere, Iwin, Alujonu, Ebora ati bee bee lo<br>LITIRESO – Kikai we litireso ti ijoba yan |
| 10 | EDE – Atunyewo eko lori ami ohun:<br>i. Kiko ami ohun Yoruba meteeta<br>ii. Alaye lori ise ti ami ohun n se ninu ede Yoruba<br>ASA – Igbagbo Yoruba nipa ori tabi eleeda:<br>LITIRESO – Kika iwe litireso Yoruba ti ijoba yan fun saa yi |
| 11 & 12 | Atunyewo lori gbogbo ise saa yii ati idanwo ipari saa keta lori Ede, Asa ati Litireso ede Yoruba |

## OSE KINNI

## AKORI EKO: AROKO AJEMO – ISIPAYA

Aroko ajomo-sispaya je aroko ti a fi n se isipaya awon ori oro to je mo ohun ayika eni. Aroko yii fi ara jo aroko asapejuwe sugbon o jinle ju u lo. Bi aroko asapejuwe se le fe ki o sapajuwe 'Ile-iwe re', aroko ajemo isipaya yoo fe ki a so nipa idagbasoke to de ba gbogbo nnkan ile iwe naa titi de ori eto isakoso. Aroko ajemo isipaya maa n tu isu de idi ikoko ijinle itumo, anfaani ati aleebu ori oro.

Eyi tumo sip e aoko ajemo isipaya pe fun imo to gbooro nipa sisafihan bi nnkan won se ri tabi sise. Ki akekoo to le yege ninu aroko ajemo isipaya, o gbodo nifee si ise iwadii nipa nnkan ayika, ki o si ma aka orisirisii iwe, jona ati iwe-iroyin, ti yoo fun un ni imo kikun nipa nnkan ayika.

Aroko ajemo isipaya le je eleyo-oro tabi apola ti won ni itumo to jinle. Apeere aroko ajemo isipaya ni:

(i) Omi
(ii) Iwe iroyin
(iii) Ise Tisa
(iv) Oge-Sise
(v) Imototo
(vi) Aso ebi

Aroko ajomo-isipaya tun le je ori-oro bii:

(i) So awon nnkan ti iwo o se ti won bay an o ni alamojuto eto iwosan ni agbegbe re
(ii) Se ekunrere alaye bi iwo yoo se seto ayeye odun ibile laarin awon akekoo ile-iwe re.

E je ki a ka aroko ajemo isipaya yii wo, bi apeere:

## OWO EYIN

Orisirisi iwa ibaje lo maa n fa Orile-Ede seyin. Okan ninu iru awon iwa ibaje bee ni gbigba ati fifuuni ni owo eyin. Iwa yiiti gbile ni Orile-Ede wa. Bi o tile je pe opo awon eniyan nla lo wa ni idi iwa yii, sibe eyi ko so di nnkan to dara. Ani ohun ti ko dara ko ni oruko meji, ko dara ni. Orisirisi oruko ni awon eniyan fun owo-eyin. Awon kan n pe e ni 'Owo-abetele'. Awon kan n pe e ni 'sowo kuduru'. Awon miiran si n pe e ni 'riba'. 'Owo ibole' ni awon kan mo on si. Oun kan naa ni won n pen i 'owo pabe' tabi 'owo ijule'. A ri awon ti n pe e ni 'egbo'. Ko si oruko ti a pe ata ti a le mu tita ata kuro. Ani ko si oriki ti a le fun iwa-ibaje yii ti o le so di nnkan rere.

Ki i se owo nikan ni awon eniyan n lo gege bi abetele. Awon miiran n ra nnkan gege bi ebun, won o si fi se riba. Bee ni a si ri awon obinrin ti won n fi ara won dipo owo abetele. Ohun ti o daju ni pe ni gbogbo kolofin awujo wa ni iwa yii ti gbile bi owara ojo. Ko si si eni ti o le gba riba ti yoo se eto. Bi adajo ba gba a, too…